# Ìjà'gbara Ìnàró: Tàbí Ìdí Tí Àwọn Ènìyàn Fi ń Dìde Rìn

*Láti ọwọ́ Ngugi wa Thiong'o/tí Kọ́lá Túbọ̀sún Túmọ̀*

Ní ìgbà pípẹ́, àwọn ènìyàn máa ń rákòrò rìn pẹ̀lú ọwọ́ àti ẹsẹ̀ wọn, gẹgẹ bí àwọn ẹranko ọlọ́wọ́ mẹ́rin mìíràn. Àwọn ènìyàn yára ju ehoro, àmọ̀tẹ́kùn, tàbí erinmi lọ. Ẹsẹ̀ àti apá súnmọ́ ara wọn ju àwọn ẹ̀yà ara yòókù lọ: wọ́n níírú igun kannáà: èjìká àti itan; ìgbọ̀nwọ́ àti orúnkún; àwọn ẹsẹ̀ àti àwọn ọwọ́ tí wọn sì ní ìka márùún lẹ́sẹ̀ àti lọ́wọ́, pẹ̀lú èékáná ní ori ìka ẹsẹ̀ àti ọwọ́ kọ̀ọ̀kan. Àwọn ọwọ́ àti àwọn ẹsẹ̀ ní irú ètò kannáà fún àwọn ìka wọn láti orí àtàǹpàkò ẹsẹ̀ àti ọwọ́ títí dé ọmọ ìka ẹsẹ̀ àti ọwọ́. Ní ìgbà yìí, àtàǹpàkò ọwọ́ súnmọ́ àwọn ìka ìyókù, òun àti àtàǹpàkò ẹsẹ̀. Àwọn ẹsẹ̀ àti àwọn apá ń pe ara wọn ní mọ̀lẹ́bí.

Wọ́n máa ń bá ara wọn gbé gbogbo ara lọ sí ibi tó bá fẹ́ lọ; ọjà, ilé ìtajà, gbòkè-gbodò orí igi tàbí orí òkè, gbogbo ibikíbi tí o nílò kíkúrò lójú kan. Kódà nínú omi, wọ́n jọ ń ṣiṣẹ́ papọ̀ láti mú ara lúwẹ̀ẹ́ tàbí wọ inú ìsàlẹ̀ ọmi lọ. Wọ́n kò ṣègbè pẹ̀lú ara wọn. Wọ́n sì tún áa ń yá iṣẹ́ lò láti ọ̀dọ̀ àwọn ẹ̀ya ara míràn, ohùn láti ọ̀dọ̀ ẹnu, ìgbọ́ràn láti ọ̀dọ̀ etí, gbigboòrún láti ọ̀dọ̀ imú, àti rírí láti ọ̀dọ̀ ojú.

Bí wọ́n ṣe ń ṣiṣẹ́ papọ̀ mú àwọn ẹ̀yà ara yòkù jowú. Inú wọn kò dùn sí bí wọ́n ṣe ń yá àwọn mọ̀lẹ́bí wọn ní ọgbọ́n orí tiwọn. Owú yìí wá dí wọn lójú sí òtítọ́ pé ẹ̀ṣẹ̀ àti ọwọ́ ló ń gbé wọn káàkiri. Wọ́n wá bẹ̀rẹ̀ sí gbìmọ̀ ṣe àrèkérekè sí àwọn méjèjì yìí.

Ahọ́n lọ yá èrò lọ́dọ̀ Ọpọlọ, ó sì múu ṣiṣẹ́ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Ó bẹ̀rẹ̀ sí n ronú síta nípa agbára àwọn apá àti ẹsẹ̀. Èwo l'ó lágbára jù, ó bèèrè.

Àwọn mọ̀lẹ́bí ẹ̀yà ara méjì, tí wọn kò bìkítà rí nípa oun tí ìkejì ní, tàbí oun tí ó le ṣe, wá yá ohùn láti ọ̀dọ̀ Ẹnu láti bẹ̀rẹ̀ sí sọ pé wọ́n ṣe pàtàkì fún ara ju ìkejì lọ. Eléyìí tún wá yí sí 'ta ni ó lẹ́wà jù'; apá gbéraga nígbà tó ń sọ nípa awọn ìka gígùn ọwọ́ rè; bẹ́ẹ̀ náà ló ń bú ìkà ẹsẹ̀ nítorí bí ó ṣe kúrú, tó sì sanra tó. Ìka ẹsẹ̀ yarí, òun náà fèsì, ó ń sọ̀rọ̀ òdì nípa bí ìka ọwọ́ ṣe tínrín tó, àwọn elébi! Eléyìí n lọ fún ọjọ́ púpọ̀, ó sì ń ṣe ìdíwọ́ fún àti ṣiṣẹ́ papọ̀ dáadáa.

Ní ìparí, ó wá dá lórí àríyànjiyàn lórí ipò agbára; wọ́n wá kọjú sí àwọn ẹ̀yà ara yòókù fún ìlàjà.

Ahọ́n ló sọ pé kí wọ́n ṣe ìdíje. Ó dára, gbogbo wọn gbà. Sùgbọ́n kíni ìdíje náà? Àwọn kan ní ìjàkadi ni - pẹ̀lú ẹsẹ̀ àti apá. Àwọn kan ní fífi idà jà ni, jíju igi sókè, sísáré, tàbí títa ayò bíi ayo ọpọ́n, sùgbọn gbogbo rẹ ni wọ́n wà dànù nítorípé ó le láti mú wá sí ìmúṣẹ,

tàbí pé ko dára fún ìkan nínú àwọn ẹ̀yà ara yìí. Ahọ́n tún sọ̀rọ̀, nígbà tó gba èrò láti ọ̀dọ̀ Ọpọlọ, pẹ̀lú èrò kan tó rọrùn. Ìkọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà ara yóò wá pẹ̀lú ìdíje kan, lẹ́yìn ara wọn. Àwọn apá àti ẹsẹ̀ fara mọ́ọ̀.

ìdíje náà ṣẹlẹ̀ ní ibi mímọ́ kan nínú igbó, lẹ́gbẹ́ odò. Gbogbo àwọn ẹ̀yà ara ló wà ní ìfura kí nkankan má baà bá ara lójijì nígbà tí gbogbo wọn ń bá ara wọn jà lọ́wọ́. Ojú wò réré fún irú ewu tó lè wà ní ọ̀kánkán. Ẹtí ṣí ara rẹ̀ láti gbọ́ irú ohùnkóhùn tó bá ń wá láti ibi jínjìn. Imú fẹ̀ ara rẹ̀ kí ó le gbọ́ òórùn irú ewu kankan tí ojú àti etí kò bá rí mú. Ahọn ṣetán láti pariwo: ìbòsí!

Ìjì fẹ́ ìròyìn ìdíje yìí sí igun mẹ́rẹ̀rin igbó, omi, àti afẹ́fẹ́. Àwọn ẹranko ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin jẹ́ ọ̀kan lára àwọn tó kọ́kọ́ kó ara wọn jọ. Púpọ̀ lára wọn ń mú ẹ̀ka igi aláwọ̀ ewé dáni láti fi hàn wípé wọn wá ní àlàáfíà. Èrò aláwọ̀ púpọ̀ ni, pẹ̀lu Àmọ̀tẹ́kùn, Ẹkùn, Kìnìún, Erinmi, Ajẹran-jeegun, Erin, Àgùnfọn, Ràkúnmí, Màálú oníwo gígùn àti Ẹfọn oníwo kúkúrú, Ìgalà, Egbin, Ehoro, Ẹmọ́, àti Eku. Àwọn tó ń gbé inú omi, Erinmilókun, Ẹja, Ọ̀ọ̀nì, fi òkè ara wọn sí etí omi, wọ́n fi iyókù sínú omi. Àwọn ẹlẹ́sẹ̀ méjì, Ògòngò, Awó, àti Ọ̀kín yán apá wọn pẹ̀lú ayọ̀; àwọn ẹyẹ ń pariwo lórí igi; kòkòrò ń ṣe tirẹ̀ ní'lẹ̀ẹ́lẹ̀. Alántakùn, Ekòló, Ọ̀kùnrùn ń rá lórí ilẹ̀ àti lórí igi. Alágẹmọ ń rìn kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́, pẹ̀lú ìrọ̀rùn. Aláǹgbá tiẹ̀ ń sáré káàkiri láì dúró s''ójú kan. Ọ̀bọ, Lámbẹ́, Ìnàkí, gbogbo wọn ń bẹ́ láti ẹ̀ka dé ẹ̀ka. Kódà, gbogbo igi àti igbó bẹ̀rẹ̀ sí ń mì síhìín-sọ́hùún, tẹríba, wọ́n sì tún dúró jẹ́ẹ́.

Ẹnu bẹ̀rẹ̀ ayẹyẹ pẹ̀lú orin:

A ń ṣe èyí láti yọ̀

A ń ṣe èyí láti yọ̀

A ń ṣe èyí láti yọ̀

*Nítorípé gbogbo wa*

*Wá láti ara kannáà*

Apá àti ẹsẹ̀ búra pé wọn ó gba àbọ̀ ìdíje náà láìsí ìjà, ìta, odì tàbí súnkẹre gbàkẹrẹ.

Apá bẹ̀rẹ̀ ìdíje kíní: wọ́n ju igi kekeré kan sílẹ̀. Ẹsẹ̀, bóyá ọ̀tún àbí òsì, tàbí àwọn méjèjì papọ̀, gbọdọ̀ mú igi náà nílẹ̀, kí ó sì jùú. Ẹ̀ṣẹ̀ méjèèjì le bá ara wọn jíròrò nígbakugbà nínú ìdíje yìí, wọ́n sì lè lo ọmọ ika wọn lẹ́yọ kọ̀ọ̀kan tàbí papọ̀ bó bá ṣe wù wọ́n láti ṣe iṣẹ́ yìí. Wọ́n gbìyànjú láti yíipo; wọ́n tìí, wọ́n ṣe oríṣiríṣi nkan síi ṣùgbọ̀n wọn kò lè múu sókè. Nípa mímú kúrò níbi tó wà tẹ́lẹ̀, nkan kan ṣoṣo tí wọ́n le ṣe ni láti gbáa síwájú díẹ̀ síi.

Nígbàtí wọ́n rí èyí, àwọn ìka yá ohùn láti ọ̀dọ̀ ẹnu, wọ́n sì fi wọ́n rẹ́rìín tàkìtì. Apá ń yan fanda bíi ẹyẹ ọ̀kín, ó ń fi ara pẹ́lẹ́ngẹ́ rẹ̀ han, ó ń fi yán àwọn yókù lójú. O kọjú sí igi kékeré yìí, ó sì múu sókè ní oríṣiríṣi ọ̀nà. O jùú síwájú gidi sí inú igbó, èyí sí mú inú àwọn olùdíje rẹ̀ àti àwọn awòran dùn. Wọ́n tún fi àwọn ìmọ̀ mìíràn han: wọ́n mú ìyẹ̀pẹ̀ díẹ̀ kúrò nínú àwo ìrẹsì; wọn bọ abẹ́rẹ́; wọ́n ṣe okunfa kékeré láti fi gbé àwọn igi nlá; wọ́n tún ṣe ọ̀kọ̀ ti wọ̃ jù síwájú gidi, àwọn oun mèremère tí àwọn ìka ẹsẹ̀ fi ń lá àlá sùgbọ́n tí kò lè ṣe. Àwọn ẹsẹ̀ kàn jókòó síbẹ̀ láti wo oun mèremère tí àwọn mọ̀lẹ́bí wọn pẹ́lẹ́ngẹ́ yìí ń ṣe. Apá àwọn awòran pàtẹ́wọ́ gidi bí àrá pẹ̀lú inú dídùn àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn ẹlẹgbẹ́ apá wọn, èyí sì mú inú bí ẹ̀ṣẹ̀ gidi. Ṣùgbọ́n wọn kò rẹ̀wẹ̀sì. Bí wọn ṣe jókòó síbẹ̀ ni àtàǹpàkò ẹ̀ṣẹ̀ ń ya òdo kékèké sínú ìyẹ̀pẹ̀, ó ń ronú ìdíje tí òun lè ti borí.

Nígbẹ̀yìn, ó wá ku fún ẹsẹ̀ àti ìka ẹsẹ̀ láti ṣe ìdánwò fún àwọn ìyókù. Tiwọn, bí wọ́n ṣe sọ̀, ṣe jẹ́jẹ́. Ọwọ́ gbọdọ̀ gbé gbogbo ara láti ìbẹ̀rẹ̀ ìkọsílẹ̀ kan sí ìkejì. Eléyìí ò tiẹ̀ le, ìka ọwọ n rò, pẹ̀lú ìgbéraga. Ó ṣe gbogbo èèyàn ní kàyéfì. Gbogbo nkan nípa ara wà ní ìdoríkodò. Ọwọ́ wà nílẹ̀; ojú súnmọ́ ilẹ̀, wọn kò lè ríran dáadáa nítorí bí wọ́n ṣe súnmọ ilẹ̀ tó. Eruku wọ inú imú, ó sì ń múu sín; ẹsẹ̀ àti ìka ẹsẹ̀ n fò lókè: nyayo juu, àwọn olùwòran ń pariwo. Wọ́n wá n kọrin pẹ̀lú inú dídùn:

*Nyayo Nyayo juu*

*Kò mà sí wàhálà*

*Fuata Nyayo*

*Kò mà sí wàhálà*

*Turukeni angani*

Sùgbọ́n gbogbo ìkọbiarasí wọn wà lórí àwọn ọwọ́ àti apá. Àwọn ẹ̀yà ara yìí tí wọ́n ń pa oríṣiríṣi idán ní bí ìṣẹ́jú díẹ̀ sẹ́yìn kò tiẹ̀ le rin ju ìwọn ẹsẹ̀ díẹ̀ lọ. Bí ó rìn díẹ̀, ọwọ́ á pariwo ní ẹ̀kún, apá yẹ̀gẹ̀rẹ̀, ó sì mú kí ara ṣubú. Wọ́n sinmi, wọ́n tún gbìyànjú díẹ̀ síi. Lọ́tẹ̀ yìí, wọ́n ya àwọn ọmọ ìka yàkàtà bóyá wọn á lè rí ilẹ̀ dìmú dáadáa, sùgbọ́n

àtàǹpàkò nìkan ló lè yàbàrá bẹ́ẹ̀. Wọ́n tún gbìyànjú láti tàkìtì ṣùgbọ́n wọ́n fagilé irú èyí nítorí pé a nílò ẹsẹ̀ láti múu ṣiṣẹ́. Ó wá di pé ìka ẹsẹ̀ náà bá bẹ̀rẹ̀ sí rẹ́rìín ẹ̀gàn. Wọ́n yá àwọn ohùn àgbà kíkẹ̀ láti ọ̀dọ̀ ẹnu láti mú wọn yàtọ̀ sí irú ohùn gooro ọmọdé tí àwọn ìka ọwọ́ lò. Bí wọ́n ṣe gbọ́ ẹ̀gàn yìí, inú bí àwọn apá gidigidi, wọ́n sì tún gbìyànjú lẹ́ẹ̀kansíi láti gbé ara rìn. Lọ́tè yìí, wọn kò tiẹ̀ lè gbé ẹsẹ̀ kan. Ó rẹ̀ wọ́n, wọ́n sì gba kámú. Inú àwọn ẹsẹ̀ dún púpọ̀ láti fi agbáraa wọn hàn: wọ́n taṣẹ̀ àgẹ̀rẹ̀, wọ́n jupá, wọ́n sáré, wọ́n tún fo sókè díẹ̀ àti síwájú láì mú ara ṣubú. Ẹsẹ̀ gbogbo àwọn awòran bẹ̀rẹ̀ sí tẹ̀ ilẹ̀ pẹ̀lú inú dídùn àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀. Àwọn apá na ọwọ́ wọn sókè láti kùn nípa bí eléyìí kò ṣe jẹ́ oun tí ó yẹ̀ láti ṣe, wọ́n gbàgbé pé àwọn ni wọ́n kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀ rẹ̀.

Ṣùgbọ́n gbogbo wọn, títí tí ó fi mọ́ àwọn awòran, rí nkan àjèjì kan nípa àwọn apá: àtàǹpàkò tó ti yapa tẹ́lẹ̀ nígbà tí àwọn ọwọ́ ń gbìyànjú láti gbé ara ṣì wà ní ìyapa. Àwọn olùdíje ẹ̀yà ara wọn ti fẹ́ bẹ̀rẹ̀ sí fi wọ́n ṣe yẹ̀yẹ́ nígbà tí wọ́n rí nkan mìíràn; ní àfikún wípé àtàǹpàkò tó yapa yìí kò jẹ́ kí àwọn ọwọ́ le ṣiṣẹ́ dáadáa mọ́, ó tún jẹ́ kí ó rọrùn fún wọn láti di nkan mú dáadáa. Irú kí l'eléyìí? Àìlera tún ti wá di oun tó ń fún ni l'ágbára láti di ǹkan mú dáadáa.

Àríyànjiyàn láàrín àwọn ẹ̀yà ara láti pinu lórí ẹni tó mókè nínú ìdíje yìí lọ fún ọjọ́ márùn-ún, ìkọ̀ọ̀kan fún ìka ọwọ́ àti ìka ẹsẹ̀. Ṣùgbọ́n bí wọ́n ṣe ń gbìyànjú tó, wọn kò le mú ẹnìkan síta gẹ́gẹ bí olúborí; ìkọ̀ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà ara ni ó ṣe dáadáa nínú oun tó mọ̀ọ́ ṣe; kò sí èyí tó lè ṣe láìsí ìkejì. Wọn wá bẹ̀rẹ̀ sí ṣe ìdárò ìronújinlẹ̀: ta tiẹ̀ ni ara na, wọ́n bèèrè. Wọ́n wá ríi pé ara gan ni gbogbo wọn l'ápapọ̀; gbogbo wọn wọnú ara wọn ni. Gbogbo ẹ̀yà ara kọ̀ọ̀kan ni ó ní láti siṣẹ́ papọ̀ láti mú nkan lọ dédé.

Ṣùgbọ́n láti ríi pé irú ìdíje báyìí kò ṣẹlẹ̀ mọ́ lọ́jọ́ iwájú, àti láti múu dájú pé wọn kò kó sí ara wọn lọ́nà mọ́, gbogbo ẹ̀ya ara wá pinu pé láti igbà yí lọ, ara ó bẹ̀rẹ̀ sí rìn ní ìnàró, pẹ̀lú ẹsẹ̀ ní'lẹ̀ àti apá l'ókè. Inú ara dùn pẹ̀lú ìdájọ̀ yìí ṣùgbọ́n yóò jẹ́ kí gbogbo àwọn ọmọdé máa rìn pẹ̀lu ọwọ́ àti ẹsẹ̀ wọn ná, kí wọ́n má baà gbàgbé orísun wọn. Wọ́n wá pín iṣẹ́ fún wọn: àwọn ẹsẹ̀ yóò máa gbé ara rìn, sùgbọ́n tí wọ́n bá ti de ibi tí wọ́n ń lọ, ọwọ́ yóò ṣe gbogbo iṣẹ́ tí a nílò láti ṣe àti láti mú oun èlò dání. Bí àwọn ẹsẹ̀ bá ṣe ń ṣe iṣẹ́ ńlá gbígbé, bẹ́ẹ̀ ni àwọn ọwọ́ a máà nà síwájú láti lo ọgbọ́n wọn láti ṣiṣẹ́ agbègbè, láti ríi

pé oúnjẹ dé ẹnu. Ẹnu, tàbí eyín rẹ̀, yóò jẹ́ẹ́, yóò sì rán-an lọ láti ọ̀nà ọ̀fun sí inú ikùn. Ikùn yóò wá fún gbogbo adùn ibẹ̀ kí ó tó dàá sí inú àwọn àmù rẹ̀ ní ibi tí àwọn adùn yìí yóò ti lọ sí gbogbo kọ̀lọ̀fín ara. Lẹ́yìn èyí, ikùn yóò wá mú àwọn oun èlò ti a ti lò tán lọ sí inú ibi ìdalẹ̀sí ní ibi ti ara yóò ti gbée lọ sí orí pápá tàbí sin-ín sí inú iyẹ̀pẹ̀ láti tún fún-un ni adùn. Àwọn ewéko yóò lòó láti wù; àwọn ọwọ́ yóò já díẹ̀ lára wọn láti fi sí ẹnu. Bẹ́ẹ̀ni, bí ayé ṣe ń yípo.

Kódà, gbogbo eré àti ìdánilárayá ni a pín sí oríṣiríṣì ọ̀nà: kíkọrin, rírẹ́rìn-ín àti sísọ̀rọ̀ ni a fi sílẹ̀ fún ẹnu; sísáré àti gbígbá bọ́ọ̀lù ni a fi sílẹ̀ fún ẹsẹ̀; a sì fi bọ́ọ̀lù àfigigbá àti àfọwọ́gbá sílẹ̀ fún ọwọ́, àfi fún ẹsẹ̀ láti sáré fún wọn. Ní eré ìje, ẹ̀ṣẹ̀ ni ó ni gbogbo pápá. Bí a ṣe ya oríṣiríṣi àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí fún oníkálukú ni ó mú ara gbámúṣé síi, kódà tí ó fi gbọ́n ju ẹranko tó tóbi jùlọ lọ nínú oun tó lè ṣe ní púpọ̀sí àti ní dídánmọ́ránsí.

Ṣùgbọ́n o, àwọn ẹ̀yà ara yìí wá ríi pé bi a ṣe ṣètò àwọn iṣẹ́ yìí sì tún lè mú ìjà wá. Bí orí ṣe wà lókè sì tún le múu rò pé òun dára ju àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tó ń tẹ'lẹ̀ lọ, tàbí pé òun ni ọ̀gá tí gbogbo àwọn ẹ̀yà ara tó wà l'ábẹ́ rẹ̀ sì jẹ́ ẹrú nìkan. Wọ́n tẹnu mọ́ọ̀ pé nípa agbára, orí àti gbogbo oun tó wà lábẹ́ rẹ̀ jẹ́ ìkankan-náà. Láti tún tẹnu mọ́ èyí, àwọn ẹ̀yà ara ríi dájú pé gbogbo ẹ̀dùn àti ìdùnnú tí ìkankan nínú àwọn ẹ̀yà ara yìí rí gbà ni ó kan gbogbo wọn lára. Wọ́n kìlọ̀ fún ẹnu pé bó ṣe ń sọ èyí t'èmi àti t'ọ̀hún t'èmi, kó mọ̀ pé ti gbogbo ara ni òun ń sọ, kìí ṣe tiẹ̀ nìkan.

Wọ́n kọrin:

*Nínú ara wa*

*Kò sí erú*

*Nínú ara wa*

*Kò sí ẹrú*

*A jọ ń sin ara wa ni*

*Àwa fúnra wa*

*A jọ ń sin ara wa ni*

*Àwa fúnra wa*

*A jọ ń sin ara wa ni*

*Ahọ́n ni ohùn wa*

*Dì mí mú kí n dì ẹ́ mú*

*A jọ ń  e ara oní’lera*

*Dì mí mú kí n dì ẹ́ mú*

*A jọ ń  e ara oní’lera*

*Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ l’ẹwà*

*Lápapọ la ń  i ẹ́*

*Fún ìlera ara*

*Lápapọ la ń  i ẹ́*

*Fún ìlera ara*

*Ìfọwọ́sowọ́pọ̀ l’ẹwà*

Èyí wá di orin akọlé Gbogbo Ara. Òun ni ara máa ń kọọ́ títí di òní, èyí ni ó sì n ṣe ìyàtọ̀ láàrín àwọn ènìyàn àti ẹranko, tàbí gbogbo àwọn tí ó kọ ijà’gbara inàró.

Bí wọ́n sì ṣe rí gbogbo oun tó ṣẹlẹ̀ yìí tó, àwọn ẹranko ẹlẹ́sẹ̀ mẹ́rin kò kọbiara sí ìja’gbara yìí. Kíkọrin kò bá wọn l’ára mu. Ẹnu wà fún jíjẹun, kìíṣe láti kọrin. Wọ́n wá dá ẹgbẹ́ tiwọn sílẹ̀ tó di ọ̀nà àtijọ́ wọn mú tí kò sì fẹ́ ṣe àtúnṣe kankan sí ìgbé ayé wọn.

Nígbatí àwọn ènìyàn wá kọ́'gbọ́n lára ìṣìṣẹ́papọ̀ àwọn ẹ̀yà ara, wọ́n ń ṣe àṣeyọrí; sùgbọ́n bí wọ́n bá rí ara àti orí gẹ́gẹ́ bíi ọ̀tá tí wọ́n ń jà, ìkan lórì ìkejì, wọn á súnmọ́ àwọn mọ̀lẹ́bí wọn tó jẹ́ ẹranko tí wọ́n kọ̀ ìjà'gbara ìnàró yìí.

---

**Kọ́lá Túbọ̀sún** is a linguist, writer/critic, and language professor. He recently co-edited a collection of essays on African linguistics. His work has appeared in various publications, including Aké Review, Brittle Paper, KTravula.com, International Literary Quarterly, The Guardian, Maple Tree Literary Supplement, and recently in *Literary Wonderlands*, an anthology edited by Laura Miller. He is the winner of the Premio Ostana "Special Prize" 2016 (awarded in Ostana, Cuneo, Italy) for his work in indigenous language advocacy. He writes in English and Yorùbá, and curates the multimedia dictionary of Yorùbá Names at www.YorubaName.com.